# TAFAWA BALEWA DI PRIME MINISTER ILE NIGERIA




ELETI OFE
A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJO




VOL. IX No. 535. ELETI - ỌFẸ LAGOS, SATURDAY, AUGUST 31, 1957. KỌBỌ MEJI (2)

## Baba, Iya ati awon omo ku aku-po.

ABẸOKUTA. A gbọ irohin wipe ọkuarin kan, ti awọn npe ni Karimu Ṣango, ati iyawo rẹ ti awọn npe ni Sikira ati awọn ọmọ wọn merin ti awọn sun ninu yara kanna, ni gbogbo nwọn di oku kilẹ to mọ.

Nigbati ilẹ mọ ni ọjọ keji, ti awọn ara ile ko ri eye wọn, ki wọn jade gẹgẹbi nwọn ti ma nṣe tẹlẹ ri, awọn lọ lati ji wọn, ṣughọn nṣe ni lẹkun wọn ti gbọin-gbọin. nwọn kan ilẹkun awọn ko si gburo ni awọn ba lọ ke si awọn ọlọpa ọba.

Awọn Ọlọpa kan ilẹkun nigbati awọn ko gburo kan, ni nwọn ba fi agbara fọ ilẹkun wole awọn si ba tọkọ taya ati awọn ọmọ wọn merin, ti gbogbo wọn ti di oku ninu ile.

A gbọ wipe awọn ologbe na danọ eda ninu ile ki awọn to tilẹkun mọri lọ sun. Awọn Ọlọpa si tun nwadi wo. boya jamba ni awọn ṣe fun awọn enia na.




**THE NATIONAL BANK Of Nigeria Limited**

Incorporated in Nigeria in 1933
Paid up Capital – £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria.
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS, NIGERIA
22 Branches throughout Nigeria including IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE, OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA, ILARO, BENIN-CITY, WARRI, SAPELE, ABA, KANO, ZARIA, JOS.
LONDON OFFICE
1 THROGMORTON AVENUE, E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell
Telephone: London Wall 4303 — Cables & Telegrams: Natbaniger, London.
Head Office Representative in London
Ernest Olubunmi Obasa—Porter
CORRESPONDENTS
NEW YORK — PARIS — HAMBURG

## Prime Minister Nigeria



Larin ọsẹ yi ni Gomina agba Sir James Robertson pe Ipade awọn enia nla-nla ni igbimọ kan ti o ṣe pataki ninu Ile igbimọ nla ti Eko, lati yan ẹniti o ba ni enia lẹhin pupọ si ori oye Prime Minister ilẹ Nigeria.

Ẹniki ọpọ enia lero pe awọn o fi jẹ oye na ni Malam Tafawa Balewa ti a nwo ninu aworan yi.

ISIMI OJO KAN

Lojọ Monday 2nd oṣu Sept 1957, ni Gomina yio fi Ọgbẹni na han gbogbo Eko Aṣoju awọn ẹgbẹ kọkan lo lọ si igbimọ na ni meji-meji.

Ọjọ Monday na yio si jẹ ọjọ isinmi fun gbogbo awọn ti o ngbe ilu Eko, ki nwọn le fi oju lọ woran eyẹ ti nwọn fẹ ṣe fun Prime Minister Eko na.

Lẹhin ti Gomina ba ti yan Premier na tan, Premier funra rẹ yio si yan awọn Minister ti o rope yio ba on ṣiṣẹ pọ fun ilọsiwaju ilu Eko.

Gbogbo awọn ijoye Minister na yio to ṣoja lati ile Gomina wa sile igbimọ, nibiti awọn ṣoja yio ṣere idaraya fun awuyewuye ọjọ na. a si fun gbogbo enia laye lati lọ woran ni ibalasa ọdan. Ọba Eko ati awọn ijoye yio wa nibẹ.

## Ijoba Tun Fi Ola Kun Oye Enahoro



Oloye Anthony Ẹnahoro ti a nwo ninu aworan yi ni ijọba Iwọ Orun ti fi jẹ oye Aṣoju ti o nmoju to eto ilu (Minister of Home Affairs) On ni ijọba yi kan na tun fi jẹ oye aṣoju fun awọn ilu ti o wa arin meji ilẹ Yoruba (Mid-west) lati ma mu ọrọ gbogbo ti o jẹ ẹdun fun awọn ara agbegbe na wa siwaju igbimọ Ijọba Iwọ Orun ni Ibadan.

Oloye yi, yio lọ si agbegbe ilẹ na yio si yan awọn igbimọ ti yio ma ba damọran nipa awọn nkan ti awọn ara ilẹ na nfẹ.

# ELETI ỌFE

A-NIJU-WỌN KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
29, Kosoko Street, Lagos "ELETI - QFE LAGOS"
P. O. Box 467 Phone 23370
VOL. IX. NO. 535. LAGOS, SATURDAY AUG. 31, 1957


## Ijoba Ghana, haba ! E Se Pele

Nigbati ijọba ilẹ Aganyin (Ghana) gba Ominira, gbogbo aiye lo ba wọn yọ, yọ, yọ. ṣugbọn nigbati aimadu ijọba Aganyin ma kọkọ ṣu, ina nla ni nwọn ṣu Haba! ijọba Ghana aṣẹṣẹ tẹsẹ kan bọ odo ọni si gan paki?

Lẹẹu lọlọ yi ni a gbọ wipe ọkunrin kan sọrọ abuku si Alaiyelewa ọba Gẹsi lara, nwọn ko titori rẹ wa a kuro nilu. Bawo ni ijọba tiṣe le duro gbọnyin bi ko ba si alatako. Ninu ilẹ igbimọ nla ti London nwọn ni alatako, kini etọ ijọba Ghana lati titori wipe awọn ẹnikan ntako on nitorina ki a wa wọn kuro nilu ti a bi wọn si ti a si tọ wọn dagba si

O yẹ ki ijọba aganyin mọ wipe bi o ti wa ni Liki beni o wa ni Gbanja, ẹgbagbeje awọn ọmọ Ghana wa nile Nigeria ti nwọn mba wa ṣelu ati awọn ti o mbe ni ipo giga, beni awọn ti on ṣe owo pelu ṣugbọn awa ka wọn si ọmọ iya wa, ati aladugbo wa.

Eyiti ijọba Aganyin ṣe yi buruju. Ohun ti ijọba Aganyin nṣe yi, ni Hitler ati Musolini ṣe nijọsi, ti o di ohun ti ijọba Ghana fi ko awọn ọmọ ilu re jade lati lọ pana agbara awọn enia buruku mejeji na.

Kinla! kini ijọba Ghana ngbe ṣire bi ọmọ ejo nwọnyi, gbogbo ijọba aiye ni ko ni inu didun si eyiti ijọba Ghana ṣe yi. A Fe ki awọn Olotu Ijoba Aganyin wo ọrọ yi daro ki nwọn simi edọ.


Your PAIN is here

*This chart shows parts of the body that suffer when your kidneys are not working properly*



DeWitt's
Kidney & Bladder Pills
act directly on your Kidneys
to clear out poisons that cause pain

A few hours after taking DeWitt's Pills you will have unmistakable evidence that this wonderful medicine is already at work—stopping

RHEUMATISM, JOINT PAINS
BACKACHE & BLADDER TROUBLES




DeWitt's
Kidney & Bladder Pills

*Praised by sufferers all over the world for over sixty years*


## Oba Alara pada sori oye

AKURE Ede koyede kan ti bẹ sile larin Ọba Alara ilu Ilara ati ọba Deji ilu Akure lori ọrọ kan. ti ekini ranri; ti ekeji si ko jale.

Ijọba Iwọ-orun fi oju ina wo ọwipe bi nwọn ko ba tete fi opin si ede koyede na o le di ọran nla lori awọn Yoruba. Nwọn pe ekini, ati ekeji lati pari ọrọ na fun wọn, ṣugbọn nṣe ni ọba Alara f'aku nwọnle. Eyi yi si je iwa afojudi si ijọba gegebi o si ti je wipe ofin wa nile lati fi kilo fun eni ti o ba hu iru iwa be.

Nwọn ṣe ofin; nwọn si mu kuro lori oye re, Lehin ọdun keje ti ko si ijọgbọn
(Wo yoku loju ewe kefa)


## Kere o!

A ti ni orişirişi ogun German to ṣeṣẹ de, fun ọpọlọpọ aisan tọkurin tobinrin. Tete wa ra tiẹ, k'o to tan.

J. A. AJAO BROTHERS

MEDICINE STORES

7, Egerton Road, Lagos.


## Ijoye Ti O Se Ti Oba Ro Loye

Apa Kẹta

Ọkunrin alagba kan wa nilu Eko niwọn ọdun 1872, ti nwọn npe ni Osuru. On lẹniti o jẹ oye Ọlọtọ nigba re. Ohun ti ijoye yi ṣe ki oba to gba fila oye kuro lori rẹ ni wiye:-

Lasiko ti ijọba oyi bo nṣe ipari ija ati ọtẹ ilu Oke, nwọn ti ṣofin wipe, iilọ ni awọn nlọ yi, lati pari gbọngbo ogun ati ọtẹ nilẹ Oke, bi o ba kan ogun jija, awọn yio ba wọn ja a, bi o ba si jẹ alafia ni-awọn yio na ọwọ alafia si wọn. Iba iranlọwọ ti awọn nfẹ lọdọ ọba ati ijoye ni wipe, ẹnikẹni ko gbọdọ ta ẹtu ibọn fun ẹnikan

Awọn olofofo mu irohin wa ba ọba Goloba wipe awọn ọmọ ọdọ Ijoye kan nilu Eko nta ẹtu fun awọn Ẹgba ni ọja Agege. Goloba ran ọlọpa inu lati ọdọ rẹ lati lọ ko awọn enia na wa.

Nigbati nwọn ko wọn de, awọn enia na dahun pe ki, Goloba ṣe awọn je je, Oloye Ọlọtọ ilu Ọtọ lo ran awọn nigba ti nwọn la agogo ipe ki nwọn maṣe ta ẹtu, awọn gbọ ṣugbọn oluwa awọn fi dandan le wipe, bi awọn ko ba lọ on yio bẹ awọn lori.

Goloba ranṣẹ pe Dosunmu lati wa fi eti ara rẹ gbọ ọrọ ti nwọn sọ yi. Nitorina ọba Dosunmu ṣe ipinnu pelu awọn ijoye lati bẹ lori, ṣugbọn ọba Goloba ko gba eyini, ṣugbọn ki o da ṣẹriya fun lọna miran

Dosunmu ranṣẹ pe oloye Ọlọtọ sinu ọsẹ Iga nwọn si gba fila oye kuro lori rẹ; nwọn fi awọn ti o lọ ta ẹtu sinu ẹwọn. Bayi ni Ọlọtọ pada sile laide fila Itiju ko si jẹ ko le jade ni arin ilu, nigbati ko si ribi rọ si, lo ba ko ẹru rẹ o si lọ se atipo nilu Ọtta, ntoripe ibẹ ni ilu iya rẹ. Ibẹ na lo si ku si.

## Orin Yoruba

Ori ndetu npete aran
Ori ade aran npete ati jọba. Agbere ni Şigidi ti o fẹ wẹ ninu ojo. Bi o ti nkan ni eti. Bẹni ẹni nya Kidiri Ipakọ ko le da duro. Bi apa ti nkan ni ẹsu nya. Agbere alaşeju pẹrẹ ni itẹ.

## Tani le ranti itan atijo nwonyi

1. Oşu Sept 5th 1927. Ọba Ademọla Alake ati Ọgbẹni J.K. Coker bẹrẹ ẹjọ pẹrẹwu ninu kotu Oke Igbein, ni Abẹokuta niwaju Adajọ M.L. Tew. Loya J.C Sizer ati Ayọdele William lo wa fun Ọgbẹni J. K Coker. Lọya O. Moore lo wa fun Ọgbẹni A.K Ajişafẹ ati Loya O. Alakija lo wa fun ọba Alake.

2. August 20, 1927. Ọgbẹni Yusufu Ọba Adewọle şalaisi ninu ile rẹ ni Oko Awo
3. Sept 4th 1927. ni a şe isin ikẹhin fun Ologbe Dokita James E. Kwegyir Aggrey, M A., P.H.D, D.D etc; ninu ile isin Ita Tinubu ẹniti o şalaisi ni ilu New York ninu oşu July 30th 1927.

4 8th Nov 1927. Oyinbo Ologun kan ti nwọn npe ni Lieut Col. F. Jenkins, C.M G., e laisi ninu ile rẹ, nwọn si şe isin ikẹhin fun ninu ile isin Colonial Church ki nwọn to lọ sin oku rẹ si Ikoyi.

5. Ọgbẹni A. Antus Williams bẹrẹ iwe irohin Daily Telegraph ni Eko lọjọ 12th oşu Nov 1927.

6. Dec. 15th 1927. ni ẹjọ bẹrẹ ni kotu Gantan ninu eyiti Oloye Onitana pe awọn ara Idumọta lẹjọ wipe on ni ki ijọba san owo ilẹ Idumọta fun. Adajọ Tew lo joko lori idajọ na, Oloye Onitana Ajosa gba awọn Loya wọnyi. Desalu, Harrison, awọn ara Idumọta gba awọn Lọya wọnyi:- Alex Taylor. Akinsemọyin, Alakija, Doherty Latunde Johnson, Kayọde Robert, ati Augusto.

7. Ni opin ọdun 1927. iye awọn ọmọ ti a bi lọdun na jẹ 2 739, iye awọn ẹni a ti o si koja lọ si ọrun lọdun na ninu Eko jẹ 1,839.

## Ọro Pataki Nipa EkO Ile

Olotu,

Ko nşe asọdun bi a ba sọ wipe bi obinrin ba ti lo agbara ti a fifun lati fi şe akoso ile rẹ, bẹni aiye yio fi ni Idẹra tabi oşi. Ilaju tabi ailaju, Imọ tabi aimọto.

Ọgbẹni ọjọgbọn kan sọ wipe, nigbati enia ba nwo ọmọ kekere kan lori ẹsẹ iya rẹ, ao ma ro li ọkan ara wa wipe, awọn ti yio ku nile aiye nigbamiran niyẹn nigbati oluwa rẹ ba pẹhinda

Iru awọn ọmọ bayi, ẹkọ ti awọn obi rẹ ba na silẹ niwaju rẹ, ni yio şe afihan iru enia ti ọmọ na yio jẹ lẹhin ọla apẹrẹ ti iya ba fi lefun ọmọ t'tun na ni ọmọ na yio gba kanri, şugbọn Baba lo nfun ọmọ ni ọgbọn ori.

Bi ọmọ ba gbe sakani ọdọ obinrin pupọju, ọmọ na le kọ iwa rere, bi iya na ba niwa rere. şugbọn ko ni lọgbọn ninu. Bi ọmọ ba si gba sakani baba r. pupọ yio ri orişi-rişi ọgbọn ati arekenda, şugbọn ko ni niwa rara. Eyiti o dara ju ni ki ọmọ ma gbe ọdọ awọn obi rẹ

Ọmọ ti obinrin ba tọ dagba yio jẹ eniti o nifẹ obinrin jọjọ, şugbọn ero rẹ ko ni koja ifẹ obinrin Eyi mu ni ranti ọmọkunrin kan ti ifẹ obinrin ko si ni agbari rẹ ni ibikibi ti o ba lọ, nşe ni awọn obinrin nde ohun ijẹ sinu awo ti nwọn nfi ranşẹ si, bi o lọ silewe, awọn o fi nkan ranşẹ si, awọn lo ba ọmọ na lori jẹ di oni oloni

Emi ni
Wahabi Adeşina

### Omo Ni eni

Ọmọ wu mi, ọmọ dun ni
Ọmọ ni tẹni.
Odumare gbe temi ko mi
Ọmọ ni tẹni.
Ọmọ ẹni ko le şedi bẹbẹrẹ
Ka fi lẹkẹ si ti ọmọ ẹlomiran
Ọmọ dun ni
Ju ka meru şele lọ
Ọmọ ni tẹni

## Ogbeni Dugdale



Eniti a nwo yi ni Ogbeni J. Dugdale eniti ijoba Gesi yan si ipo asoju awon ile ti o wa labe abo Gesi laipe yio si ti bere ise re.

### Alo o, alo

1. Gbogbo ile sun, Kanbo ko sun? 2. Mo woyi woyi nko ri Nando? 3. Oruku bi gba omo, o yo kobako le won lowo?

## Afami Ilu Kura



Awon eniti a nwo ninu aworan yi ni ogbeni Eni Njoku ti o nse Minister Mine ati Power, nigbati o lo se ayewo omi ti nwon amu nilu Kaduna. Ogbeni H. Brace ti o nse olotu omi na, lo nse alaye fun Minister na ninu ohun gbogbo ti o ba bere. Awon Tips wagon li e ko edu wa sibi afami na ni a nwo lokere. Omi ti nwon nfamu na lowa lowo otun.

# Sir John Macpherson



Ninu ọdun yi, ijọba Gẹsi yio ṣe ipade igbimọ kan, eyiti nwọn npe ni (Summer Conference) ninu ile ẹkọ ti awọn npe ni Kings College ni Kembrij (Cambridge) nilu Oyinbo. Ipade bere ni ọjọ Monday 26th oṣu Aug. si ọjọ 7th oṣu Sept 1957.

Ẹniti yio ṣe Alaga ipade na ni Sir John Macpherson, eniti o kọkọ je oye Gomina Agba nile Nigeria. Ohun pataki ti nwọn fe ṣe ipade na le lori ni wipe, ninu ijọba ile enia dudu ọna wo ni awọn ọba ati ijoye yio ko ni inu iṣelu ile na nigbati a ba ti fi ijọba ominira le wọn lọwọ.

Ninu ipade yi gbogbo awọn oyinbo ti o ti ṣe iṣe Ajele kekere ati agba tabi ti o ti ṣiṣe labẹ ijọba ile Nigeria ri tabi ti o ni mimọ pataki nipa iṣesi awọn ara ile Africa ni yio wa nibe. Ki ọrọ ti nwọn fe sọ yi ba le ye awọn igbimọ na yekeyeke nwọn o ṣe aworan iṣesi ati ilosi nwọn ọba ilẹ Yoruba ati awọn Hausa. Olukuluku awọn aṣoju na yio bere sijibin nipa awọn ohun ti o mọ nipa awọn ọba ati awọn ijoye ti a wa mi agbegbe ibiti o gbe ṣiṣe lasiko ti o aṣiṣe nile Nigeria.

Dokita Margery ni yio ka itan iṣe ti Luguard ṣe nile Nigeria nigba aiye rẹ. Agbo wipe awọn oyinbo kọbitakọbita ti o ti ṣiṣe ri, ti o si ni oye nipa awọn ile enia dudu jake jado yio so ti ẹnu wọn, ati ohun ti nwọn mọ nipa ilu ti nwọn ti ṣiṣe gbogbo.

# Alapara Ibadan nki yin o

OKE FỌKỌ
Ibadan

Iwe wosika kan ti mo ri gba ni ijẹta tabi ijaren tilẹ ni? Ọlọrun ni yio sa gba mi pẹlu ki nma gbagbe ọjọ ti mo wẹ, ọjọ ti mo jẹ iyan ati ọjọ ti mo jẹ amala ọpọlọpọ ni awọn ọrẹ mi ti inko tilẹ mọ orukọ wọn mọ. Nko ṣe were, agba lo de si mi—ewu ori mi ko nṣe ti irọnu-agba ni. Ni oju mi ni Shittu ṣe jẹ Balẹ ni ilu Ibadan, mo si mọ Alafin Ọyọ—Shinyabọla Ladigbolu ni mo wi o. Ọrọ temi Alapara Ibadan wa di meji ni Afin Ọyọ.

Mo ba Babayeye Shinyabọla Ladigbolu lọ igba nisisiyi ọba Gbadegunẹsi lo ku ti mo mba jaiye aiye ọba ni mo njẹ, kirijin ki Ẹyin na ko wa ripe temi di meji ni Afin Ọyọ.

Ẹ wa na, wosika ti mo ri ni ijọ wo niyi ni mo fẹ ki ẹ ba mi ka, nitoripe enia mẹta si mo haya, ti mo ni ki wọn ṣe ọnigbọ-ọ mi lati ba mi ka ki wọn si tumọ rẹ fun mi. Yoruba ni wọn nkọ; ọwọ akọwe na wa dabi igbati ẹdiẹ kọwe ti Oyinbo wa ka ti. Iwe wosika na ni eleyi:—

"Alapara tabi bawo ni o ti pe ara rẹ? Otu ni ẹ, iran rẹ ko gbodọ ba wa sọrọ nilu Iṣẹyin, nitoripe iranṣẹ ni ẹ jẹ fun wa ni agbegbe wa. Mo gbọ wipe Otu ni ẹ, ọrọ ẹnu yin pẹlu bi ẹ ti nṣe si ni o nmu iya jẹ yin nilu yin. Mo fi awọn iya yin fun amodi sobia ti o nwọ yin lẹsẹ. Arun sobia na ni yio ṣe yin lẹsẹ.

Awọn aboyun yin ṣẹṣẹ bere iya jẹ ni o. Ẹ kọ ile Abiyamọ ko si omi ti ẹ o fi ṣe iṣẹ nibẹ. Iyẹn na to fun yin.

Emi "Ọmọ Abẹdi"

Emi ko le ba arakọnrin ti o kọwe si mi ti o pe ara rẹ "Ọmọ Abẹdi" wi nitoripe mo mọ awọn ara Iṣẹyin ni "Ọmọ Abẹdi" ilu ẹyẹ kiki ẹgan. Bi o ba ṣe temi Alapara Ibadan ni, ebu kọ so. Ẹ jọwọ, ẹ ma ṣe ki gbe mi pupọ—otitọ ọrọ ti Alapara Ibadan nsọ ṣugbọn aiyekotọ. Ọmọ Abẹdi, wa tun ri omiran kọ ko si ni rẹ emi na lati mọ sọ otitọ fun nyin t'apara t'apara. Ọkọ ọba ko si ni ṣe mi lẹsẹ.

Alapara Ibadan nki nyin o.

# Kereni Nla (Carter Bridge)

Lati ọjọ 27th oṣu August ni kereni nla (Carter Bridge) ti bere si ti lati agogo meji oru di agogo mẹta fun ọsẹ mẹta. Moto nika ṣoṣo ni ko ni gbodọ rin lori Kereni ni asiko ti a wi yi, awọn ẹlẹṣẹ ati oni Basikulu le koja. Ko si idilọwọ fun wọn.

Ijọba fẹ ma fi wakati kọkan na ṣe atunṣe Kereni na ni.

# Tani gbe oyun mi lo o!

A gba o ori ede! kini a ti npe eyi? ẹ fun mi, tabi edi? Ohun ti oju yio ri ni Eko ti Adele yi, ko ma ni kere!

Ni owuro ọjọ Alamisi ni a ri odidi gbajumọ kan baale, beeni ti o nsare kiri ninu poto-poto Ebute Ero wipe ye, ye, ye, o gbe mi ni oyun lọ, tani ba mi ri aboyun kan ti o gbe ẹru leri. Ib si are! Tani gbe oyun ọkunrin yi lọ o?.

Awọn Oniwe irohin susmọ, awọn bere Patiwa lọwọ ọkunrin na. O dahun pe lati ọjọ ti on ti nfẹ obinrin ko si eyiti o loyun fun on lati owuro di alẹ ri, titi ti on fi dagba ti on si nhu ewu lori ki obinrin kan, Kogbede to jaja ni oyun fun on.

Ko si iboti ri ni bi enia ba gun ẹṣin ninu agbẹdu ikun on, gẹgẹ bi ẹṣin na yio kọja lọ. Nigbati o jepe Ọlọrun ti owo fe on lọrun ti on si jaja ri enikan ti o loyun fun on bayi, kini on tun nwa? Nje ni on bere si kẹ loju, kẹ nimu.

Ko ni aṣọ ọlẹ, apoti bembe mẹfa ni o kun fun aṣọ ti mo ra fun, mo ra yaya orun ati ẹgba ọrọ ati yeri eti. Bata jorsirisi gbogbo ni mo ra fun ni iru eyiti awọn enia le fi mọ wipe iyawo gbajumọ lo mbọ yi.

Ṣugbọn titi obinrin na fi ko gbogbo awọn ẹru nwọnyi tan nko fura ṣaaju ṣimọ awọn apoti ti mo nwo ninu ile, ofifo ni gbogbo wọn.

Gbogbo awọn ti ko tilẹ dun mi bi ti oyun mi ti o gbe lọ. Ha! ori mi ba wa ṣe aṣedanu nile aiye nibi. Awọn ẹbi mi gbogbo lo ti hinmọ ti mo si ba wọn ṣe ẹye. Eyiti o si ti ro on royi fun [illegible] na ni awọn gbe lọ yi.

Eleti-Ọfẹ gba ni imọran pe k'o maṣe bẹru lọ. Bi o ba pẹ titi ọmọ yio wa baba rẹ kan. Emi l'ẹhulọ.

## Bere - bere Ki Isi Here

OLOTU. Jọwọ gba mi laye lati fi ibere itumọ owe Yoruba yi siwaju awọn ọkawe wa aladun yi.

Ekini:- Aiye dun nigba gbogbo igba ogurọ ni ke awọn.

Ekeji :- Enia buburu pọ o ju igbe, enia rere wọn o ju oju lọ.

Ejọwọ mo fẹ ki enini o ba mọ la itumọ awọn owe na ye mi.

Emi ni
Y. Ade Buraimọ

## Emi Mimo Gbe Aladura Kan Lule O Ku Bamu-bamu

Eko Losan gangan ojo Sunday 25th osu August 1957 ni a gbo irohin bayi wipe, okunrin Aladura kan ti ijo Holy Flock of Christ nilu Eko wulu dede subulule gbel larin ijo isin, lasiko ti o nse wasu lowo.

Awon elegbe re jro wipe emi mimo lo gbe lo bayi, sugbon asehinwa asehinbo nse nj aladura na di ero orun.


## Imoran Fun Enyin Abiyamo

Enyin abiyamọ ẹ wa ra ỌMỌRELA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama jẹ ki ọmọde ri orun sun daradara o dara fun otutu, ikọ ati orisirisi arun miran ti o ma mba ọmọde ja ni asiko ehin. Ọpọlọpọ abiyamọ lo ti lo egbogi yi fun ọmọ wọn ti wọn si sọ wipe o dara pupọ fun awọn ọmọde

ỌMỌRẸLA BABY MIXTURE

(Ṣile Meji Abọ 2/6d Fun Igo Kan)

O wa Lọdọ
COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemist)
10, VICTORIA STREET, LAGOS.


## Awujo Awon Prime Minister



Awon eniti a nwo ninu aworan yi ni Prime Minister awon ilu ti a ti fun ni Ominira ninu won ni Ogbeni Nkruma wa, ti o nse Premier fun ilu Ghana, on lo fi aso bora gegebi asa isedale awon Aganyin. On ni eniti ogba ominira fun ilu re tan, ti o bere si wa awon Oselu ati awon Oniwe Irohin jada kuro nilu. Ohun ti a gbo wipe awon enia na se ni wipe, awon ntako Nkruma ti o nse asi waju ilu Ghana,

No. 73/S2/503

## Ministry Of Development Western Region

VACANCY FOR ASSISTANT POTTERY OFFICER

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment to the post of Assistant Pottery Officer, Western Region.

Salary: Scale C (T) 1,2,
£408 x 18 - £510;
£570 x 24 - 744. Point of entry will depend on the experience of the applicant.

Qualifications: Cambridge School Certificate or suitably equivalent and evidence of experience in the pottery industry.

For further particulars and method of application see Western Region of Nigeria Gazette No. 38 Vol 6 Notice No. 765 of 15/8/57.

Closing Date:
Overseas Candidates: 29/8/57.
All other Candidates. 5/9/57.

No 121

## Public Lotteries

"Members of the public are warned that the organisation of, or participation in public lotteries (except lotteries exempted by law) is an offence under the Criminal Code and will result in the prosecution of the offenders.

Conviction may result in a find of £50 or imprisonment for six months".

N. K. MILLETT.
COMMISSIONER OF POLICE
CENTRAL REGION.

## Awure Bamwo




Omo t'o mu Bamwo ki ku. Omo t o mu Bamwo ki s'okunrun ........

Bi nwon ba s'erepa l'osan nwon, a sun fonfon l'oru. Awon l'owere ji t'on torin, odaji jeun bi emó. On li a da f'abiyamo kendere pe ki o rubo abiku, ki o ma wa Bamwo ra kiri.

Nje iku si Bamwo mo. Sinimo-sinimo arun si Bamwo mo Sinimo-sinimo " Wa ra Bamwo fun omo re lode wa. Igo kekere 2/6d Igo nla 4/- Owo oko 1/6d fun igo kan.

**The Egba Trading Aradan Stores**
18, Denton Bridge Street,
P. O. Box 2, Ebute Metta & Branches Phone 44153.

**Let's have MUSIC! HEAR THE LATEST HIT NUMBERS**

**Read this list of popular titles**



JZ 6077–Omo sola Savage/Igba Laiye
" 6078–Aiye Akamara/Iwa Rere Leso Enia
" 6079–Gbo Adura Wa Baba/Irele Lo Laiye (Rosey Show Mambo Orch)
" 6080–Gba Wa Lowo Ota/Iberu Olorun S. O. A. Ladipo and His Koranic Group
" 6082–Olomo Lo Laiye/Feso Jaiye
" 6083–Shogbola/Wellington Ade-Ade & His (Juju) Orchestra.

JZ 6088–Owo Lowo Agbara Ke/Abiba Alase
" 6087–Ori Lo Yomi/Saka Ilorin Aminu Olaribigbe & His (Sakara) Band
" 6089–A Gbere Wa De/Awon Kokokeko- Taiwo Abuna & His (Apala) Band
RJZ 100–Ma Pami/Zambesi (In Afro-Cubol)
RJZ 101–Bowo Ba De/Adaku (Ibo)
RJZ 102–Ma Doyiabo/Igbuem Iwem (Itsekiri) (Ibo)

*Sold by all the best stores*

**"HIS MASTER'S VOICE" *Yellow Label* RECORDS**

HIS MASTER'S VOICE

Distributed by THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street P. Box 467 Lagos Phone 23?70